## KÁÀDÌ RẸ ÌTỌ́JÚ RẸ

Tọ́jú káàdì Medicaid rẹ ní ọ̀nà

tí o fi ń tọ́jú káàdì Ààbò Ìgbàlódé tàbí àwìn rẹ—máṣe **yá** tàbí tàá fún ẹnikẹ́ni. Tọ́jú rẹ sí ibi ààbò bi o ti ń tọ́jú owó tàbí ìwé sọ̀wédówó rẹ—tí o kò jẹ́ kí ẹnikẹ́ni ríi.

Máṣe ṣàpínlò káàdì Medicaid rẹ, Nọ́mbà Medicaid, tàbí àlàyé ìtọ́jú ìlera míràn pẹ̀lú ẹnikẹ́ni tí kò ní àṣẹ láti níi. Àlàyé yìí ni o gbọ́dọ̀ ṣàpínlò pẹ̀lú dókítà, ilé-ìwòsàn, ilé-ìtọ́jú, ìsọ̀ ògùn, tàbí olùpèsè ìtọ́jú ìlera míràn nìkan.

Tí o bá furasí wípé ẹnìkan ń gbìyànjú láti lo káàdì Medicaid rẹ láì gba àṣẹ tàbí nọ́mbà, fisun Ibi-iṣẹ́ ní Ọ̀gá Àgbà Medicaid. Èyí pẹ̀lú ẹnití ó kàn, ìgbà tó ṣẹlẹ̀ irú ìwà ibi wo lo ṣẹlẹ̀ àti bóyá àwọn ẹlẹ́rìi wà sí ìṣìwàwù náà.

O tún le jábọ̀ ìtànjẹ tí o furasí láì lórúkọ. Ṣùgbọ́n pípèsè orúkọ àti àlàyé ìbánisọ̀rọ̀ míràn yóò ṣèrànwọ́ fún olùwádìí tí wọ́n bá nílò àlàyé síi.

**877-87-FRAUD**
**(877-873-7283)**

NEW YORK STATE

## Office of the Medicaid Inspector General

www.omig.ny.gov



NEW YORK STATE | Office of the Medicaid Inspector General

# Títọ́jú Káàdì Àti Nọ́mbà Medicaid Rẹ



# Dáàbò bo ara rẹ. Dáàbò bo ètò rẹ.

# Dáàbò bo káàdi àti nọ́mbà Medicaid rẹ.

Ìtànjẹ Medicaid kìíṣe ọ̀ràn tí kò ní ẹnití a dálóró. Àmọ̀ọ́mọ̀ tan ènìyàn jẹ tàbí ṣíṣe aṣojú ẹlòmíràn lọ́nà èké fún àwọn ànfàní tí a kò fún láṣẹ le fi ìtọ́jú ìlera rẹ sábẹ́ ewu, fi dọ́là àwọn ènìyàn tí ń sanwó-orí ṣòwò, èyí sì lòdì sí òfin.

Ohun kan tó le ṣàkóbá ìtanjẹ Medicaid ní ṣíṣe àpínlò káàdì Medicaid rẹ tàbí nọ́mbà pẹ̀lú ẹnikẹ́ni yàtọ̀ sí dókítà rẹ, ilé-ìtọ́jú, ilé-ìwòsàn, tàbí olùpèsè Medicaid rẹ míràn.



### *ÀWỌN ÌDÍ TÍ A FI Ń ṢÀPÍNLÒ NỌ́MBÀ TÀBÍ KÁÀDÌ MEDICAID NÍ Ọ̀NÀ ÀÌTỌ́*

- Ṣíṣe ìrànlọ́wọ́ fún ọ̀rẹ́ kan tàbí mọ̀lẹ́bí tó nílò rẹ̀ ìtọ́jú ìlera ṣùgbọ́n tí kò ní ìtọ́jú ìlera adójútòfò.
- Títà tàbí ṣíṣe ààrọ̀ káàdì tàbí nọ́mbà fún owó, ọjà, tàbí àwọn iṣẹ́ tí kò bá Medicaid mú.
- Lílo káàdì Medicaid ní ọ̀nà àìtọ́ bíi ìdánimọ̀ ara-ẹni.
- Dídáhùn ìlẹ̀kùn sí ìlẹ̀kùn tàbí ìtajà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àwọn ènìyàn tí ń bèrè káàdì Medicaid tàbí nọ́mbà.
- Pípèsè káàdì tàbí nọ́mbà Medicaid sí àwọn àjèjì tó fẹ́ fún ọ ní àyẹ̀wò ìlera ọ̀fẹ́, idánwò, tàbí àwọn ẹ̀bùn míràn.
- Dídá ààbò bo ara rẹ lọ́wọ́ ẹnìkan tí ń halẹ̀ mọ́ ọ tàbí ẹbí rẹ tí o kò bá ní ṣàpínlò káàdì tàbí nọ́mbà Medicaid rẹ.



### *ÀWỌN ÀBÁJÁDE TI ÀPÍNLÒ KÁÀDÌ TÀBÍ NỌ́MBÀ MEDICAID NÍ Ọ̀NÀ TÍ KÒ DÁRA*

- Àlàyé ìlera tàbí àdáni ti ẹlòmíràn ni a le fi sínú àkọsílẹ̀ ìlera rẹ èyí si le jásí àṣìṣe nígbàtí o bá nílò ìtọ́jú.
- Medicaid le má sanwó fún ìtọ́jú ti o nílò tí wọ́n ti sanwó tẹ́lẹ̀ fún ìtọ́jú kannáà fún ẹlòmíràn.
- O le ní láti sanwó padà fún Medicaid.
- Ìwọ tàbí ẹlòmíràn tí n lò káàdì rẹ le san ìtanran tí ó tó ọdún mẹ́wàá ní ọgbà ẹ̀wọ̀n àti owó ìtanran $500,000 fún gbígba káàdì tàbí nọ́mbà Medicaid láàyè fún àṣìlò.

## KÍNNI O LE ṢE?

***TÍ O BÁ FURASÍ WÍPÉ ẸNÌKAN Ń LO KÁÀDÌ MEDICAID RẸ TÀBÍ NỌ́MBÀ NÍ Ọ̀NÀ ÀÌTỌ́,***

# Fi Ìtànjẹ náà Sùn!

**Ibi-iṣẹ́ Ọ̀gà Àgbà ti Medicaid**
Àjọ Ìfisùn Ìtànjẹ Medicaid
800 North Pearl Street
Albany, NY 12204

**Nípa ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀:**

**877-87-FRAUD**
**877-873-7283**

**Tàbí lórí wẹ́ẹ̀bù:**

**www.omig.ny.gov/medicaid-fraud/file-allegation**